# IPÒ ALUFAA TI AARỌNI ATI KRISTI

**Ẹksodu 28:1-5; Lefitiku 8:1-36; 9:22-24;**

**Heberu 7:11-28; 8:1, 2**

**ẸKỌ 84 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori a jẹri pe, Iwọ ni alufa titi lai nipa ẹsẹ Mẹlkisedeki" (Heberu 7:17).**

### Idi ti a fi Gbọdọ ni Alagbawi

Ninu iwa mimọ́ Ọlọrun ati kikún ti eniyan kún fun ẹṣẹ, o ti di dandan pe ki ẹni kan duro ni aarin iwa-mimọ́ Ọlọrun ati awa ti o kun fun ẹṣẹ lati bẹbẹ fun wa. Ọlọrun korira ẹ̀ṣẹ, O si ṣe ofin pe, "Ọkàn ti o bá ṣẹ̀, on o kú" (Esekiẹli 18:4). Ṣugbọn Jesu ti mura tán lati ru ẹbi wa ati lati kú dipo wa. O ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki awa ba le ni irapada ayeraye. Nisisiyii O wà niwaju Ọlọrun lati maa bẹbẹ fun olukuluku ẹni ti o bá bẹbẹ fun idariji ẹ̀ṣẹ rẹ̀. "Bi ẹnikẹni ba si dẹṣẹ̀, awa ni alagbawi lọdọ Baba, Jesu Kristi olododo" (1 Johannu 2:1).

Kò le ṣe e ṣe fun wa laelae lati ri Ọlọrun pẹlu ẹ̀ṣẹ ninu ọkàn wa. A ni lati dari ẹ̀ṣẹ wa ji wa ki Oun to le gbà wa, ki O si wẹ̀ wọ́n nù. Lẹyin eyi, nigba ti Ọlọrun ba ri Ẹjẹ naa pe o bo ọkàn wa, O le fi ifẹ wo wa. Kò si ọna miiran ti a le gbà wá si ọdọ Ọlọrun. Nigba ti Jesu wà ni ayé O wi pe, "Kò si ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipasẹ mi" (Johannu 14:6). Itumọ eyi ni pe bi Jesu kò ba fi Ẹjẹ Rẹ̀ bo ọkàn wa, Ọlọrun ki yoo gbà wá gẹgẹ bi ọmọ Rẹ̀. Nigba ti a ba dariji wa, ti a dá wa lare niwaju Ọlọrun, a kò tun ni dẹṣẹ mọ́.

### Ẹjẹ Awọn Ẹranko jẹ Apẹẹrẹ Ẹjẹ Jesu

Awọn eniyan ti wà ni ayé fun ẹgbẹẹgbẹrun ọdun sẹyin ki Jesu to wa si ayé lati kú fun ẹlẹṣẹ. Bawo ni awọn wọnyii ti ṣe le ri igbala? Lati atetekọṣe ni Ọlọrun ti ni eto pe awọn eniyan le pa ẹran, ẹjẹ rẹ̀ yoo si ṣe etutu fun wọn. Ẹjẹ maluu ati ewurẹ jẹ́ apẹẹrẹ Ẹjẹ Jesu ti yoo ta silẹ lati mú ẹ̀ṣẹ kuro.

Nigba ayé awọn baba nla igba nì, ki Israẹli to di orilẹ-ède, awọn olori ni idile kọọkan ni o n ṣe gẹgẹ bi alufaa, wọn a si ṣe irubọ fun ẹ̀ṣẹ ara wọn ati ti awọn ọmọ wọn pẹlu. A ṣe akiyesi pe Jobu maa n ji ni owurọ kutukutu o si maa n rú ẹbọ sisun fun awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbinrin rẹ pe boya wọn ti dẹṣẹ, wọn si yẹ fun ibinu Ọlọrun (Jobu 1:15).

### Awọn Alufaa Israẹli jẹ Awojiji Jesu

O jẹ ohun iṣoro fun awọn Ọmọ Israẹli ni akoko ti wọn lati moye eto irapada eyi ti Jesu yoo sọ di mimọ̀ nigba ti O wá si ayé, nitori eyi Ọlọrun fi Ofin fun wọn ninu eyi ti Agọ Ajọ wà pẹlu eto ati ilana isin inu rẹ̀, ati awọn alufaa ti o maa n ṣe eto isin mimọ́ rẹ̀. Gbogbo eto isin naa jẹ awojiji ti o n tọka si Jesu, wọn si n ṣe apẹẹrẹ ohun ti yoo ṣe nigba ti O wá si ayé lati kú ni Kalfari lati san owo irapada, ki O si mu wa ri oju-rere Ọlọrun.

Nigba ti o kù diẹ ki Jakọbu kú, lẹyin ti o ti wá si Egipti pẹlu ẹbi rẹ̀, o pe awọn ọmọ rẹ̀ mejila si ọdọ rẹ̀ lati bukun wọn; o si sọ asọtẹlẹ pe ọmọ oun akọbi ki yoo ṣe olori awọn Ọmọ Israẹli ti yoo maa rú ẹbọ fun awọn iyoku ninu ẹbi. Lẹyin eyi, nigba ti awọn Ọmọ Israẹli dẹṣẹ nipa ṣiṣe ẹgbọrọ maluu ti wọn si fori balẹ fun un, awọn ẹya Lefi wá si apa kan si iha ti Oluwa; lati inu ẹya yii ni a ti yan Aarọni lati jẹ́ olori nipa ti ẹmi fun orilẹ-ède yii ki o si maa ṣe iṣẹ isin gẹgẹ bi olori alufaa. Awọn iran rẹ̀ nikan ni o le ṣẹ iṣẹ-iranṣẹ ni ipò alufaa.

### Ṣiṣe E lọṣọ fun Ipò Alufaa

Ọlọrun paṣẹ fun Mose lati dá ẹwu daradara fun Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀, lati maa wọ̀ nigba ti wọn ba n ṣe iṣẹ isin wọn ni ibi mimọ́. Ọlọrun funra Rẹ̀ ni o ṣe apejuwe ẹwu wọnyii, eyi ti a fi aṣọ ọgbọ wiwẹ́, alawọ́ wura, búlù, elese aluko, ati pupa ṣe, ti a si fi ọgbọn awọn oniṣọna dárà sí lara. Awọn aṣọ wọnyii wa fun "ogo ati ẹwà," wọn o si ṣe awọn alufaa wọnyii lẹṣọọ fun iṣẹ wọn niwaju Oluwa ninu Agọ.

Awa ti ati tun bi lọjọ oni jẹ́ alufaa fun Ọlọrun, aṣọ daradara ti a si fi ṣe awọn Ọmọ Ọlọrun lọṣọ jẹ aṣọ òdodo: "O ti fi agbáda wọ̀ mi, o ti fi aṣọ ododo bò mi, gẹgẹ bi ọkọ iyawó ti iṣe ara rẹ̀ lọṣọ́, ati bi iyawó ti ifi ohun ọṣọ̀ ṣe ara rẹ̀ lọṣọ́" (Isaiah 61:10).

Lẹyin ti awọn alufaa ba ti wọ aṣọ daradara wọn, wọn ni lati ṣe ifararubọ ki a si sọ wọn di mimọ́ ki wọn to le ṣe irubọ fun awọn eniyan. Gbogbo ijọ ni yoo wá sinu Agọ Ajọ lati wo eto isin eyi ti a o fi sọ Aarọni ati awọn ọmọ rẹ di mimọ́. Fun ọjọ meje ni wọn wà ninu Agọ ti wọn n ṣe ohun ti Ọlọrun ni ki wọn ṣe. Wọn fi omi wẹ ara wọn, a fi ororo yà wọn si mimọ́, wọn si ṣe irubọ si Oluwa. Wọn pa akọ maluu kan fun ẹbọ ẹ̀ṣẹ, ati agbò kan fun ẹbọ sisun ati agbò miiran fun ifararubọ wọn. Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ gbé ọwọ́ wọn le awọn ẹran yii lati fihàn pe awọn ẹran naa yoo kú ni ipò wọn.

### Ifararubọ Wa

Ọlọrun ni o fi gbogbo irubọ wọnyii lelẹ, wọn si ni lati ṣe wọn gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi gan an, ki Aarọni ati awọn ọmọ rẹ ba le ṣe iṣẹ alufaa wọn. Yoo jẹ́ ohun ajeji fun wa bi awa ba ni lati lọ sinu gbogbo eto isin yii; ṣugbọn awa naa ni nnkan lati ṣe ki a to le sọ wá di mimọ́. A kò ṣẹṣẹ ni i fi ẹran rubọ, ṣugbọn a ni lati jọwọ ara wa ni "ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwọgbà, eyi ni iṣẹ-isin nyin ti o tọ̀na" (Romu 12:1). A ni lati kiyesara bakan naa lati ri i pe a jọwọ ohun ti o wu Ọlọrun fun Un. Kò ni inu didun si ifararubọ ti a kò fi tọkantọkan ṣe. A ni lati fi eyi ti o dara ju ninu ayé wa fun Un, ki a si ṣe ileri lati ṣe ohunkohun ti O ba ni ki a ṣe.

Ju pe a fi ororo ya awọn alufaa sọtọ a tun ni lati fi ẹjẹ si eti ọtun wọn, atampako ọwọ ọtun wọn ati atampako ẹsẹ ọtun wọn. Eyi n fihàn pe a fi ẹjẹ bò wọ́n. A n kọ́ ẹkọ nihin yii pe Ẹjẹ ni lati wá sinu ọkàn wa lẹẹkan si i ni akoko isọdimimọ́, lẹyin ti a ba ti di "alufaa," eyi nì ni pé nigba ti a ti gbà wa là.

**Iná ti o Tayọ Òye Eniyan**

Awọn alufaa wà ninu Agọ fun ọjọ meje nigba ifararubọ wọn. Ni ọjọ kẹjọ wọn ti wà ni imurasilẹ lati ṣe irubọ fun awọn eniyan. Ọlọrun fi hàn pe iṣẹ isin ati ifararubọ wọn tẹ́ Oun lọrun nigba ti O rán iná sọkalẹ ti o jó ẹran ti o wà lori pẹpẹ. Eniyan kọ́ ni o tan iná naa. Ọlọrun ni o mu ki o bẹrẹ si i jó lojiji. Inu awọn eniyan naa dùn pupọ pe Ọlọrun wà pẹlu wọn to bẹẹ ti wọn fi doju bolẹ ti wọn si yin In.

Nigba ti a ba n fẹ́ isọdimimọ́, ti a si ṣe ifararubọ ti o wu Ọlọrun, Oun yoo jẹ́ ki iná ti ẹmi bọ́ sori ẹbọ wa, a o si mọ̀ pe a sọ wa di mimọ́. Sibẹ ibukun ti o ju eyi lọ ni o n duro de wa ninu ifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni, nigba ti a ba fi agbara lati ṣiṣẹ isin wọ ẹni ti a ti sọ di mimọ́.

Iná ti Ọlọrun dá ni a mu ki o maa jò titi lori pẹpẹ. Ni owurọ ati ni alẹ ni a n fi ẹbọ titun sori rẹ̀, yatọ si ọpọlọpọ akanṣe irubọ. Bẹẹ gẹgẹ ni awa naa maa n mu ki iná ifẹ Ọlọrun maa jò ninu ọkàn wa nipa riru ẹbọ ifẹ ati iṣẹ isin atọkanwa lojoojumọ si Ọga Ogo.

**Olori Alufaa Wa**

Gbogbo awọn alufaa ni o ni iṣẹ lati ṣe, wọn a si maa ṣiṣẹ ni isowọ́pọ̀ pẹlu olori alufaa, ẹni ti i ṣe aṣaaju wọn. Awọn nnkan kan wà ti o jẹ pe olori alufaa nikan ni o le ṣe wọn. A jẹ́ alabaṣiṣẹ pọ̀ pẹlu Kristi Olori Alufaa wa nigba ti a ba n tan Ihinrere kalẹ. Jesu ni Ori Ijọ, Oun nikan ṣoṣo ni O si le gba ẹni ti o sọnu là.

A mọ̀ pe lati inu ẹya Juda ni Jesu ti wá, "nipa ẹ̀ya ti Mose kò sọ ohunkohun niti awọn alufa" (Heberu 7:14). Bawo ni O ṣe le jẹ́ alufaa bi awọn alufaa ba jẹ́ lati inu ẹya Lefi?

Alufaa kan ti wà rí ti o tobi ju Aarọni lọ. O jẹ́ alufaa ni akoko ti Abrahamu. (A ranti pe Abrahamu ni baba nla Jakọbu, lati inu ọmọ Jakọbu eyi ni ni Lefi, ni Aarọni ati ipò alufaa ti jade). Alufaa yii ni Mẹlkisedeki, a si n pe e ni ọba Salẹmu. Nigba ti Jesu dé, Oun kò ṣẹṣẹ ni lati wá lati idile Aarọni, ṣugbọn O jẹ́ alufaa bi ti Mẹlkisedeki ẹni ti i ṣe ọba pẹlu. Jesu yoo jẹ́ Ọba nigba ti O ba pada wá lati jọba ni ayé ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun.

Abrahamu jẹ́ eniyan nla, eniyan Ọlọrun, ẹni ti a n pè ni baba igbagbọ́. Awọn akọwe ati awọn Farisi pe e ni baba wọn, wọn si ka a si olupilẹṣẹ ẹsin wọn. Ṣugbọn ni ọjọ kan bi o ti n pada bọ̀ lati ogun pẹlu ọpọlọpọ ikogun, o pade Mẹlkisedeki, bi o si ti kà a si ẹni ti o tobi lọpọlọpọ ju oun lọ, Abrahamu san idamẹwaa fun un. Mẹlkisedeki si sure fun Abrahamu. Paulu sọ fun wa pe ẹni ti o kere ni i maa san idamẹwa fun ẹni ti o tobi ju u lọ, ẹni ti o tobi ju eniyan lọ ni o si maa n bukun ẹni naa; a le ri i pe Mẹlkisedeki tilẹ tobi ju eniyan nla Ọlọrun yii, Abrahamu.

**Kristi, Alufaa gẹgẹ bi Mẹlkisedeki**

Mẹlkisedeki jẹ apẹẹrẹ Jesu, nitori naa bi Mẹlkisedeki ba tobi ju Abrahamu lọ, dajudaju Jesu tobi ju Abrahamu lọ. Awọn akọwe ati awọn Farisi kò fẹ́ lati feti si ọrọ Jesu, wọn n wi pe awọn ni Abrahamu ni baba. Ṣugbọn Jesu wi pe, "Abrahamu yọ̀ lati ri ọjọ mi." Gbogbo awọn wolii Majẹmu Laelae ni o n fi ayọ̀ wo ọna fun igba ti Jesu yoo dé, ti ki yoo tun si wiwá alufaa bi ti Aarọni mọ́.

A ranti ninu ẹkọ nipa Agọ Ajọ pe a ri ifarahan Ọlọrun pe O wà laaarin awọn Kerubu lori Itẹ Aanu ni Ibi Mimọ́ Julọ. Olori Alufaa nikan ṣoṣo ni o le wọ yara yii lọ, ati eyi paapaa ni ẹẹkan lọdun. Ṣugbọn nigba ti Jesu wá si ayé awọn Ọmọ Israẹli ti fa sẹyin kuro lọdọ Ọlọrun to bẹẹ ti Ifarahan Ọlọrun kò tun wá si Ibi Mimọ́ Julọ mọ́. Nigba ti Jesu kú lori igi agbelebu, aṣọ ikele ti o bo Ibi Mimọ́ Julọ faya lati oke de isalẹ, olukuluku si le wọle. Igba isin ti agọ ati ti Tẹmpili ti kọja. Jesu ni Olori Alufaa titun, Oun kò si ni i ṣe irubọ ẹran ninu Tẹmpili lojoojumọ, nitori O ti fi ara Rẹ̀ rubọ lẹẹkan, O si ti ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun etutu ti o duro titi lae; O si wọ Ọrun lọ pẹlu Ẹjẹ Oun tikara Rẹ̀.

**A Fi Ororo Yan Kristi gẹgẹ bi Alufaa**

Jesu kò di alufaa nitori Oun kàn n fẹ́ lati di alufaa. Ọlọrun ni O yan An, gẹgẹ bi O ti pe Aarọni (Heberu 5:4). A wẹ Ẹ ninu omi a si fi ororo (Ẹmi Mimọ́) yan An nigba ti a ṣe iribọmi fun Un lati ọwọ Johannu Baptisti) ni odo Jordani, ti Ẹmi Ọlọrun sọkalẹ sori Rẹ̀ bi adaba. Ẹjẹ ti o wà ni eti, atampako ọwọ, ati atampako ẹsẹ awọn alufaa ni a mu ṣẹ nigba ti Jesu dé ade ẹgun ti a si fi iṣo dá ọwọ ati ẹsẹ Rẹ̀ lu nigba ti a kan An mọ agbelebu. Jesu mu apẹẹrẹ ipo alufaa ṣẹ: ṣugbọn wò o bi titobi Rẹ̀ ti ta eyi ni yọ pupọ to!

Nigba ti Isaiah ri iran Oluwa, o gbọ́ bi awọn kerubu ti n ke: "Mimọ́, mimọ́, mimọ́, li OLUWA awọn ọmọ-ogun, gbogbo aiye kún fun ogo rẹ̀." Isaiah dahun pe: "Oju mi ti ri Ọba, OLUWA awọn ọmọ-ogun" (Isaiah 6:3, 5). Eyi ni Jesu Ẹni ti O ti di Olori Alufaa wa. Johannu pẹlu, lori erekuṣu Patmo, gbọ́ awọn angẹli n kọrin pe; "Yiyẹ li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukún"; gbogbo awọn ẹda ti wọ́n wà ni Ọrun ati lori ilẹ aye, ati nisalẹ ilẹ, ati irú awọn ti wọ́n wà ninu okun, dahun pe: "Ki a fi ibukún ati ọlá, ati ogo, ati agbara fun ẹniti o joko lori itẹ́ ati fun Ọdọ-Agutan na lai ati lailai" (Ifihan 5:12, 13). Jesu, Olori Alufaa wa, fi ara Rẹ̀ rubọ gẹgẹ bi Ọdọ-Agutan Ọlọrun, lati fun wa ni iye ainipẹkun. Oun n ṣipẹ nisisiyii fun wa niwaju Ọlọrun. Gbogbo awọn ti o bá wá pẹlu ironupiwada ti wọn si beere idariji fun ẹ̀ṣẹ wọn ni a oo dalare niwaju Ọlọrun nipasẹ Ẹjẹ Jesu, wọn yoo si ni iye ainipẹkun.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti a ni lati ni alufaa?
2. Ta ni Olori Alufaa wa, bawo ni Ipò Alufaa Rẹ̀ ṣe sàn ju ipò alufaa ti Aarọni lọ?

3. Bawo ni a ti ṣe n yan awọn alufaa ni Agọ si ipò yii?
4. Njẹ iran Aarọni ni Jesu i ṣe bi?  Nipasẹ ta ni Oun i ṣe alufaa?
5. Bawo ni Jesu ti ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ?